Irohin Yoruba

# Ọwọ ọtun Ọlọṣa fo sọnu

*Ojo gbogbo ti ole ojo kan ni ti olohun ni o difa fun olosa ti o padanu owo otun re, ti o si fi oju ati ese pa nigbati awon olosa merin lo gbogun ti ode kan ti nise ni ile ifowo pamo si Barclays Bank ni ilu Bompai. Okunrin na tin runmu ni ile iwosan Kano nisisiyi.*

Gegebi a se gbo lati odo awon olopa, Ogbeni Danu Agadas ti o je ode ni awon ogboju olosa merin lo kamo enu ise re sugbon nigbati ode na fi igbo ta awon mesa sa lugbo, meon ju okan ninu won sehin, eyiti o ro nimu ara re pe on le se ohunkohun fun ode na.

Olopa tun fi kun pe larin ifi agbara ko agbara ni ogboju olosa na ti padanu owo otun re, ti o si fi oju ati ese pa yankanyankan.

# JAMBA MỌTO GBẸMI MẸFA

## Alaake

(Lati oju ewe kini) ni idi re ti nwon fi ntiraka lati gba Ijoba Agbedemeji Ipinle Iwo Orun si ki Ipinle na ba le di eru amunisin fun won, nwon si ti si lokan pe dandandan owo awon yio te ceku ida Ijoba na, yala lona ti o mo ni o, tabi lona jamba.

O ni egbe Alakoko ti pinnu lati ja ija ajaye ninu ibo gbogogboo ti o mbo yi, pelu ajumosowopo awon Osela Olododo ki awon eru amunisin lowo egbe Olomi le di ominira.

IKA ENIA

Ogbeni Amechi ni gbogbo egbon jamba egbe Olomi ni o ti han si awon patapata.

O ni asiri iwa aiyederu enia kika ni Ipinle Ariwa ti awon Ajele Gesi igbana ka ninu odun 1952 tu han gbogbo enia nisisiyi nitoripe awon enia ipinle na ko po to iye ti nwon kaa si ni odun 1952, sibesibe awon koi ti to apapo iha Gusu. O tun so siwaju si pe nigbati egbe Olomi rii pe ipo adanikanjopon ko si fun won mo ni Ile Igbimo Asofin; ti nwon si mo daju pe ki o to to osu die si, ssungbugbe yio ba won, ni nwon ba nwa orisirisi ona titun lati fi gba agbara pada.

*ỌJỌ burúku esu bome mu ni ojo Isegun ti isi ojo kejidinlogbon osu k ni odun yi je ni Ibadan ninu orisirisi oko mefa ti enia mefa ku, awon mewa si farapo pupo.*

Ikini ṣtẹfa to ni o fa ijejade oko na larin ibuso kejila si ketala lona Iwo si Ibadan

Isele keji ni eyiti o sele ni ona Oyo si Ibadan, ninu eyiti o gba emi enia merin, ti meje si farapa sugbon ojoko na wa ni ikawo awon olopa nisisiyi.

Isele oko miran ti o tun sele ni eyiti o gbemi omobinrin Ijo Aguda kan ti oruko re nje Mary Cyprian eniti o ku sinu Ile Iwosan ni kete ti o de be.

Mary je oga kan ni ile Iwosan Alabiyamo Aguda "Catholic Maternity". O pade iku ojiji nigbati o nbo lati Enugu nibiti oko ayokele re ti fori so oko akeru kan ti o nbo niwaju re ni ibuso meji si Oturoba.

## Ajọse di Bada Ilọra

Olori ile eko giga Unifasiti Ife, Ojogbon Oladele A. Ajose yio di Bada Ilora nibi ase kan ti nwon o se ni Ilora nitosi Oyo ni ojo Abameta ti ise ojo kejo osu keji odun yi.

Dokita Ajose ti je ojogbon nipa eko ogun ajesara ni ile eko giga Unifasiti tele ki o to bo si ile-eko giga Unifasiti Ife.




Ogbeni B.P. Bindy ti ise igbakeji oga awon olopa ni Freetown Sierra Leone ni o wa ni ipo kini ni owo osi ninu aworan oke yi nigbati a nko eko pataki ni ile oyinbo, Ogbeni P. Grierson ti ise olopa lati ilu Lancashire ni o wa larin, Ogbeni Gaberones lati Bechuana wa ni owo otun. Nwon njiroro lori ofin irinna moto.

## EWI JARE ALAWẸ

NI ejo Aje ti ise ejo ketalelogun osu kini odun yi ni Adajo Ile ejo ganran Naijiria ni ejo kotemilorun eyi ti Alawe ti Ilawe Ekiti, Oba A. Adefolalu pe ti o fi nro ile ejo giga na lati gbesele ejo ehi ti ile giga Akure da lori ija ile kan ti on ati Ewi Ado-Ekiti, Oba Aladesanmi ti ndu fun igba pipe ka.

Adajo ile ejo ganran na si ni ki Oba Adefolalu lo san pounn marun pele marun owo irinse fun Ewi.

Adajo ile ejo giga Akure Ogbeni V. Akin-Delano ni o da ejo eyiti Oba Adefolalu nfe ki ile ejo ganran gbe ese le.

Ninu idajo na, ile ejo giga Akure gba pe Oba Aladesanmi, Ewi Ado-Ekiti ni eniti o ni ile ti o wa larin Ado ati Ilawe Ekiti lori eyiti awon Oba mejeji yi ti nja le fun odun die sehin.

Awon Adajo ile ejo ganran ni ejo yi ka lori idani loju pe agbejoro Oba Adefolalu

Oloye B.O. Olusola ko fi awon koko ti o fi ese rinle siwaju ile ejo, ti o le mu ki awon gbo ejo kotemilorun na.

Adajo ile ejo Akure da ti ejo kotemilorun kan ti o pe si ile ejo na ka bakanna.



OBA ALADESANMI (KEJI)


# NOW-ROLLS-ROYCE 707s ON THE LONDON RUN




## Eto irinajo ayarabiaṣa ti ojojumọ

NISISIYI oko ofurufu titun ti a npe ni Rolls-Royce 707 ti wa fun awon onirin ajo ti o nlo si Londonu ati awon ile Oyinbo. Rolls Royce ti a mo jakejado aiye fun ero ti o dara julo ti o se ero ti o ngbe oko ofurufu yi fo bi eiye Fun igbadun ati itura nigbati o ba nrin irin ajo ninu oko ofurufu ayara bi asa, kesi Travel Agent re tabi ki o bere ni Nigeria Airways Booking Office ti o wa ni Broad Street, P.O.Box 136. Lagos (Telephone 24811) bi ni Bank Road, P. O Box 11, Kano (Telephone 3891—tabi awon ile ise oko ofurufu ni agbegbe re.

NIGERIA AIRWAYS

NIGERIA'S NATIONAL AIRLINE


Published by the Eastern Post Limited, Elephant House 214 Broad Street, Lagos and printed for them by the African Press Ltd, P. O. Box 78, Ibadan, Editor: E. O. OLOFIN, c/o 98, Shittu Street, Ibadan